# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ A/YE. TẸNI GBOGBO LAWA

No 770 FRIDAY AUGUST 14 1964 (2D)


## Egbẹdogun Ponun Eru S'Egbe Ninu Jamba ina

ONISHA:- O di pẹntuka ni ọjọ ru tise ọjọ kejila osu yi nigbati jamba ina nla kan sẹlẹ ni ile iṣẹ Ọgbin ni Ogidi l'ẹba Onisha eyiti awọn ẹru toto bi ẹgbẹdogun ponun s'egbe ninu jamba ina nla na, gbogbo awọn ile nwọn nko awọn ero ti ile iṣẹ oko ọgbin na si lo si jona patapata ti ko si ku okankan silẹ.

Gbogbo awọn to wa ni adugbo ile iṣẹ oko ọgbin na ni Ogidi l'ẹba Onitsha ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria lo bẹrẹ si sare ti ọlọmọ ngbọmọ ti nwọn ko si ni iranti ati ko awọn ẹru wọn ti gbogbo awọn enia na nsare lati da abo bo ara wọn nigbati jamba ina na ṣẹlẹ ni ọjọ na.

Ninu ọrọ ti Ọga agba ni ile iṣẹ na ni Nkweke Ọgbẹni F C Obiọha fi ye oniwe Irohin wato wa ni Onitsha pe jamba ina na ṣẹtẹ ni ọsan gangan ọjọ na eyiti o fa gbogbo awọn ile to wa ni oko Ọgbin ni ti ẹru bi ẹgbẹdogun Poun si ṣegbe ninu jamba ina na.

Ọgbẹni F. C Obioha tun fi ye Oniwe irohin wa pe awọn ko mọ ohun to fa jamba ina na ti wa titi di isisiyi

# AMECHI NA SARDAUNA NI PASAN ỌRỌ

ABAKALIKI:- Alakoso eto ọkọ oju omi fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati akọwe eto irohin fun ẹgbẹ Alakukọ N.C,N.C, ọgbẹni Mbazulike Amechi sọ ninu ọrọ rẹ ni Abakaliki pe Alakoso Ijọba ipinlẹ Ariwa ati olori ẹgbẹ Olomi N.P,C. Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna ti Ilu Sokoto ngbayanju lati pa ilẹ Naijiria pọ mọ ilẹ awọn Arab.



Alhaji D. S Adegbenro
Asiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ọgbẹni Amechi sọ ninu ọrọ rẹ pe gẹgẹbi Ọlọla Alhaji Amadu Bello ti ngbero lati da ilẹ Naijiria pọ mọ ilẹ Arab, ọgbẹni Amechi sọ pe Alhaji Ahmadu Bello fi nhan pe ti on ba le bori lori eto ọro oṣelu pe on yio ni agbara lati le pa ilẹ Naijiria pọ mọ ilẹ awọn Arabs,

Ọgbẹni Amechi na ṣe ikilọ pe ẹgbẹ on NCNC ki yio gba ẹgbẹ oṣelu kan kan laye ti yio jẹ alatako si ẹgbẹ nwọn laseko idibo si ile Igbimọ asofin ti apapọ Ijọba gẹgẹbi aṣiwere oṣelu bi ko ṣe pe awọn yio gba gẹgẹbi ọta si gbogbo orilẹ ede ilẹ Naijiria pata

Ọgbẹni Mbazulike Amechi ba awọn oniwe irohin sọrọ lẹsẹkẹsẹ ti o ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ se ipade kan tan ni ilu Abakaliki ni ọjọ ru ti ṣe ọjọ kejila osu yi nibi ti on pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti nse eto lori idibo to nbọ yi.

Ọgbọni Amechi tun fi ye awọn oniwe irohin pe eto nipa gegebi nwọn yio ṣe yan ẹniti yio gbe apoti ibo sile lasiko idibo si ile igbimọ aṣofin ti nbọ yi si fẹ ohun to jẹ pe awọn ọmọ ẹgbẹ ko to ba wa ni agbegbe ibi ti nwọn yio ti yan awọn enia ti yio gbe apoti ibi silẹ lo jẹ pe awọn enia agbegbe rẹ lo ni ẹtọ



Dokita M. I. Okpara
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

lati yan ẹni to ba wu awọn enia na ati pe ki iṣe eto ẹgbẹ lati mu enia silẹ bi ko ṣe awọn enia Oluwa rẹ.

Nigbati Ọgbẹni Amechi ba awọn oniwe irohin nsọrọ lori rogbodiyan to ṣẹlẹni ilu Abakaliki, Ọgbẹni Amechi ṣe ikilọ pe ẹnikẹni to ba gbe apoti ibo silẹ pe on yio dibo ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti yio so pe on yio duro gedegbe Ọgbeni Amechi sọ pe ara rẹ ni yio da lẹbi ni ikẹhin.

Ọgbẹni Amechi to rọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ lati ni ifarada lati ri pe ẹgbẹ Alakukọ yio ṣe akoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria laseko ti nwọn ba ṣe idibo si ile Igbimọ asofin ti apapọ Ijọba Naijria

Ọgbẹni Amechi sọ pe nigbati ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre ti apapọ bayi, oni o da on loju pe awọn ẹgbẹ mejeji na yio bori ọta wọn patapata,

Oniwe irohin wa fi ye wa ninu irohin rẹ lati Abakaliki pe ohun ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ se ipade le lori ọka ninu ọmọ ẹgbẹ

Wo Oju Ewe Kẹfa.



Alhaji Ahmadu Bello
Olori Ẹgbẹ Olomi

## Awọn Ehanna Egbẹ Oṣelu Gbogun Ti Awọn Ọlọpa

IBADAN:—Ọrọ di pentuka ni ibudo awọn Ọlọpa ti Ijọba ibilẹ ti Ilu Ibadan nigbati awọn ọlọpa ibudo na bẹrẹ si sa asala fun ẹmi wọn nigbati awọn Ẹhanna ẹgbẹ oselu kan romọ ibudo awọn ọlọpa na ni adugbo Mọnkọla, Ibadan ni ọjọ ru tise ọjọ kejila osu yi.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe ohun to fa rogbodiyan na wa ni Alakoso eto oye fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Iwọ Orun, Oloye Saka Layọnu ti awọn Ẹhanna ẹgbẹ oselu na lọ kọlu nigbati Alakoso na fẹ pada lọ si ile rẹ ti awọn Ẹhanna da a du o ninn mọto rẹ ti nwọn si bẹrẹ si ni na Oloye Layọnu eyiti o fi jẹ pe nwọn gbe e lọ si ile iwosan fun itọju ni irọlẹ ọjọ na.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe nigbati awọn Ọlọpa mu ọkunrin kan ninu awọn Ẹhanna ẹgbẹ oselu ti nwọn fi kọ lati gba iduro rẹ ni awọn ẹhanna ẹlẹgbẹ rẹ si rọ wọ inu ile ibi ti nwọn fi ọkunrin na pamọ si ti nwọn bẹrẹ si lu awọn ọlọpa ti nwọn ba ni ibudo awọn ọlọpa na titi awọn ọlọpa na fi sa asala fun ẹmi wọn,

Oniwe irohin ṣe alaye ninu irohin rẹ pe ọkan ninu awọn ọlọpa to wa loju ọna lati le ma toju ọna fun awọn onimọto tete lọ si ibudo awọn ọlọpa na lati lọ dekun rogbodiyan na sugbọn nigbati o ri pe ọwọ on ko le ka a lo ba lọ kesi awọn ọlọpa ẹgbẹ rẹ lati le wa dẹkun rogbodiyan na.

Awọn ọlọpa na tun fi ye onirohin wa pe lẹsẹkẹsẹ ti rogbodiyan na ti ṣẹlẹ ni awọn ọlọpa nkan ni ibu-

WO OJU EWE KẸFA

# AYUNỌRUNBỌ ATI PAPALANSO (Apa Kejila)

**Ibiti mo ba itan yi de ni ana ni bi awọn ọrẹ Ayunọrunbọ ṣe sun ori Ojola mọju ti wọn ko si mọ pe ori Ojola ni awọn fi ṣe ibusun.**

LATI ỌWỌ

**J. O. Shoyinka**

Wara wara ti Ojola wo, iwokuwo li o wo wọn, wọn si fi ara bo yannayanna, inu bi Ojola yi nigbati o ri pe ori on ni awọn ọrẹ Ayunọrunbọ sun moju, o ni ha! ẹgbin yi ma pọ ju o abajọ ti gbogbo ara fi nro mi, ẹhin mi paapa ti fẹ rẹ kan a ṣe ẹnyin ẹẹkọ Ọlọrun yi lẹ ẹ fi mi ṣe busun nyin, ti ẹ si fi mi ṣe irọri bẹni ẹ mọ pe ẹda ọwọ Ọlọrun ni emi na gẹgẹbi ti yin ẹjẹ ti o wa lara nyin li o wa lara emi paapa, jẹjẹ ni mo si joko sinu Ọgbun yi, nkogbun enia ẹnyin lẹ wa ira ẹ o si ri ngo ban nyin ni koro eomọ loni ẹnyin enia buburu y Bi o ti sọrọ tan ni ọkan da lohun ninu awọn ọrẹ Ayunọrunbọ pe Kabiyesi Ojola K a b i y e s i Ọba ejo laiṣe aniaŋiohun ti o gbe nyin de ihin ni o gbe awa papa de ihin pẹlu bi ati le ṣe de inu Ọgbun yi ako le sugbọn, wọ ti aja sinu ọgbun yi ako tilẹ mọ ibiti awa afi igbuti oyi da loju wa, ako si mọ pe ori rẹ li asun la, Baba nla Boba wa ha le sun le ọ lori bi? Anbọsibọsi awa lasan lasan yi kabiyesi ako mọ ni o, Odi ẹlẹkeji ti ẹṣu ti ntan wa Lakọkọ iya ti ajẹ ko ṣe fi ẹnu sọ, Eyiti atun njẹ lọwọ nisisiyi eṣu na lo tun sun wa si Ajule Ọrun ni a nlọ, ki eṣu totan wa ihin ade arin meji afara ni oba ṣe gbura bi a ti ṣe dibe i ni yi o.

Ojola kanu wọn, o ni mo dari jin nyin o. ṣugbọn ọrọ nyin wa dasa ọrọ akukọ nigbati oba fẹ kọ ani kekereke-e-e! kekereke-e-e!! kekereke-e-e!!! mo bọ lọwọ ẹkọ-ọọ. Ti o ba bọ lọwọ ẹkọ, njẹ oba bọ lọwọ iya bi? ti ọ ba bọ lọwọ mi, awọn Omiran (Giants) rọgba si nyin ke yi nkọ apọn gan ni Olori ọgbun yi kosi si ẹda alayekan ti o wọ ilu yi ti o fi ara rere lọ Ẹtẹwọ Adura ki e ba yọ gọnọgen wọn da lohun pe tirẹ loju ti ọwọ arẹ ba yọ ko sewu rara, Ojola dagbere fun wọn, osi wọ lọ si Iho gbungbunrun kan,

AWỌN OMIRAN ṢU YỌ

Ko pẹ ti o ra wọ inu iho tan, awọn Omiran su yọ ọkọkan ninu wọn ga to ẹsẹ mejilamejila, aya wọn ri jagilajagila, atari ri ragaji bi ti Erin, Olukuluku wọn bẹrẹsi mi fin fin-fin fun ibinu Atẹgun.

ti o ngba iho imu wọn jade li o ko gbe awọn ọrẹ Ayunọrunbọ wọnlẹ olori awọn omiran jade sita o ni ẹnyin enia raurau nyin yi kini ẹ wa de ihin? Ohun ti oju nyin yio ri ko ni kere, ẹniti o ba fẹ wadi ohun ti o nsọrọ ninu radio ni ọrọ nyin, yio ba nkan jẹ, ofin wa si ni yi:- Ẹnikẹni ti o ba sina wọ abule yi apafọn ni a npa wọn, iku oro ni ẹ o ku nisisiyi ẹ ko gbi ẹsẹ wa duro, ṣugbọn kekere inu wa ni yio ba nyin ja, ẹmura ikude ki omiran miran to to bẹ sita kia, Oni mitotọ ẹda ọwọ Ọlọrun ni nyin, ẹ ko si lagbara ju Ọlọrun Ọlọrun papa si kọ ileri, ni agbara Edumare ẹ ko ni ri wa gbeṣe wara nṣe sa, wọn ti de wọn n adesẹhin wọn na wọn ni ina kuro gbogbo ara w ọ n s i l e patipati, o nṣẹjẹ wuruwuru, wọn si fi ata kun wọn lara bi ẹni kesun, ara nta wọn gboo wọn bẹrẹsi ke irora, nigbati o ya wọn tu wọn silẹ, wọn ni kekere ni iya ti ẹjẹ yio, babanla iya nbọ wa jẹ ẹyin papa, wọn tin yan omiran ka ti o lag b a r a j n l ọ n i n u wọn sita lati ba awọn ọrẹ Ayunọrunbọ ja ki oto kan wọn lara tun awọn ọrẹ Ayunọrunbọ ti s u ru bo wọn bi idan wọn ti gbe wọn le ara rẹ ṣi ti se gbogigbogi inu bi omiran yoku wọn fa ẹsẹ yọ bi wọn ti nju ẹsẹ si awọn Ọrẹ Ayunọrunbọ bẹni wọn nyeẹ i d a r u p ọ de, ibinu ti mu ki oju wọn ṣokun kun wọn bẹrẹ si kan ara wọn lẹsẹ ọrọ na wadi awọn ara wọn ko sai ba ara wọn ja. Awọn ọrẹ Ayunọrunbọ wa fiditi wọn nfi wọn ṣe yẹyẹ bayi ni awọn Ọkunrin lọwọ rẹ, o poora mo wọ loju,

Moti ṣe ileri lọsẹ to nbọ ng'o bẹrẹ ni bi Ayu ọrun ti fa wọn soke ati bi eṣu tun t fe tan wọn jẹ lẹẹkẹ a Ekeji:- [illegible] ti o tun berepe b ya mo ti tẹ itan WO OJU EWE KARUN


make it a successful
SEASON
*with* MERCEDES - BENZ
TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

# IWE SI OLOTU

## Ọrọ L'ori Awọn Woli

Olotu inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye *k*ekere ka*n* lati ba awọn WOLI "OPURỌ" sọrọ nitoripe ọpọ aṣiṣe ti wa ndo gba si lori ile aiye lode oni.

Eyin ara mi ninu Olu a, inu mi yio dun pupọ bi e ba le f ori-ji mi *l*ati ba awọn ,'Woli opurọ" sọr, bi gbol*o*hun kan eyi ti o lọ bayi pe, ni aiye isisiyi awọ*n* ajẹ nirun Woli ti o gbe awọ enia wọ ti o si jẹ kinniun on ikok*o* ninu rẹ lo kun ode aiye, ti ẹ ba ri ira awọn Woli ba yi nwọn a wọ aṣọ bi *ti* "HAUSA" gb*o*-gbo rẹ a ma gba ile Li a ṣọ egun-gu*n* nwọn a si m ke kakiri ode loru nwọn o ni jẹki ara ilu sun ti o si wipe gbogbo ọrọ Ọlọrun i o nsọ ko wa ni ọkan rẹ sugbon ki o ba le ṣe oju aiye ki awọn enia rẹ ma ba s, ọ lẹnu ṣe ni yio ma gba toru gbe l*o*ri iwasn ki Oluwa gba wa lọwọ awon Ajẹni*r*u ẹda Woli ti o gbe awon enia wo ti gbo-gbo ero inu rẹ si jẹ i k o k o on kinniun,

Ẹ jowo ẹnyin *e*nia mi ni*n*u Olu-wa, mi o so wipe ko si W O L I ODODO sugbon awon opuro ati atan ni jẹ Woli lo p*o* lori'lẹ aiye ti nwon ba so pe a w o n ma wo ẹnikan san, awon a gba owo *t*abi lowo rẹ.

Jaburata asẹ*h*in wa asẹhinbo alarẹ atun ku ojẹ Jesu Kristi ngba owo ohunkohun kan lọwọ enia mi ẹ jẹ ka ṣe ifẹ baba loke nitorina asan lori asan ni,

Mo fẹ bere ohun kan,, mo ma nṣe akiyesi kan, mo ma nri i ti awọn W*o*li ba ngbadura nwọn a ma tan Abẹla, nibo ni eyi wa ninu Bibeli pe ki a ma *lo* abẹla nigbati a ba fẹ gbadura ? tabi ti a ko ba lo abẹla adura wa ko le gba ? Lotọ awọn P*e*ter tan ina nigbati nwọn wa ninu tubu ki nwọn ba le riran ka ọrọ Ọl*ọru*n ṣugbọn Bibeli ko sọ fun wa pe ki a tan abẹla silẹ ti a ba fẹ gba-dura. nit*o*rina ẹnyin Woli ododo mo fẹ gbọ ọrọ lori ibere mi ni-nu Irohin *I*mọlẹ ni aipẹ yi.

Awa ti a jẹ onigbagbọ, ẹ jẹ ki a mura giri ki a tun ẹsin wa ṣe nitoripe gbogbo afẹ aiye yi asan ni.

Ogun aya ni mo ni, ọgbọn ale mo nya, o dijọ o ba pubulẹ t'opojuhe ti iwọ o le dide; ha ! ọjọ lọjọ na a ku'wọ a ku'wa re, ẹniti a wi fun ko gbọ. *B*ibeli sọ ninu ọrọ rẹ pe "Ẹniti a nba *wi* ti o nwa ọrun ki, yio paru , loji-j lai si atun e"

Emi ni,
Gabriel

MUSH N.

## Malawi Gba Ominira



Orilẹ ede Nyasaland gba Ominira ni ọjọ kẹfa oṣu keje ọdun yi ni dede agogo mejila oru Ọjọ ti [Orilẹ Ede Nyasalandi yi Orukọ Ilu na pada si Malawi

Ilu Malawi ni odi llẹ enia Dudu kẹtadinlogoji ti yio gba Ominira,

Ni Owurọ ọjọ na ni Ọmọba Philip ti o ṣe Aṣoju Ọba binrin Gẹẹsi nibi ẹyẹ Ominira na ka ọrọ moba ọ yọ fun Ijọba ilẹ Malawi ati awọn onia Orilẹ ede na Ọmọba Philip fun Ala-koso Ijọba Orile ede Malawi Dokita Hastings Banda ni ami Ohun aṣẹ eyiti Ọba binrin Gẹẹsi Elezabeth keji fun ọmọba Philip lati fun Alakoso ilẹ Malawi.

Aworan Oku yi fi Ọmọba Philip han nigbati oba Omidan Cecilia Kadzamira Akọwe Aṣiri fun Dokita Banda njo nibi Ẹyẹ Ominira na ni Alẹ ọjọ na ni Blantyre.

Wo Oju Ewe Kẹrin fun Aworan Miran.

## Enyin Aṣẹwo Eko, Ẹma Baiye Jẹ o

Olotu mo fẹ ba awọn aṣẹwo eko sọ gbolohun ọrọ kan inu mi yio si dun ti ẹ ba tete ba mi *g*be ọrọ na yẹ si nwọn ni kiakia yi ki nwọn ba l*e* mọ ohun ti nwọn nṣe.

*A*wọn agba a ma pa owe kan ti o lọ bayi pe "Ti ara ile *e*ni ba njẹ kokoro buburu, ti a ko ba dan lẹkun, kuru-kẹrẹ rẹ ko ni jẹ k'le-nia sun loru" nitori ẹnyin ṣẹ*wo* ilu sko ki ẹjowọ ki ẹ *r*anti ọjọ ati e'ọr*u*n nyin Ọlọru*n* Ọba ko ni fi iya aisododo nyin jẹ nyin o mo rẹ ki ẹṣ*o*ra gidigidi ki ẹsi rori nyin ki ẹṣe eyi ti o to ati eyi tio yẹ nitiripe g ogbo nkan ti ẹ nṣe wonyi afẹ aiye lasan ni.

Ni a*l*ẹ ana ti mo nti oju irin bo mo pade awon aṣẹwo meji pẹlu awọn ọmọ kunrin meji ti nwọn nlọ ni oju titi mo ṣe akiyesi awọn enia wọnyi dada ma si wo wọn finni-fi*n*ni, N*i*nu awọn asew*o* me-ji yi ọkan wọ aṣọ osi ti nwọn pe ni mafogota, o yọ irun rẹ' iyẹn wa sokun dududu bi igbo Aginju o tun nkanan ni ibadi, o bo bata onişo iyẹn dun han-han lori titi Ọlọda o wa kun ẹnu rẹ o pọn do-do bi aṣọ sango o fi ag*o*go *s*i owọ .si pẹlu ilẹkẹ t,ogamuṣe si orun o wa nyidi biribiri bi ẹniti o ti fi itau da, *ha*! ki Ọlọrun ma fun wa ni Olori buru ọmọ o, ẹnikeji rẹ tun ṣe ju *e*leyi lọ nwon wa nrẹ-ri musẹn si aw*on* okunrin meji yi, nwon a tun g*b*e ori si won laya bi nwọn ti nrin lọ awọn oniyẹn na di tayi mọrun nwọn nfa ra wọn mọra, lọ mọ ara wọn loju titi ki ẹnyin aṣẹwo Eko jọwọ ki ẹ*ma* ba aiye jẹ o.

Bibeli sọ bayi pe Ẹniti a nbawi ti o nwa ọrun ni, yi*o* parun lojiji lai si atun ṣe , ti aba wi fun nyin ti ẹ ko gbọ ao si bẹ Ọlọrun si nyin ki O ba wa bẹ nyin, Ki *o*si dari aisododo ny*i*n ji nyin

Emi ni
G*a*briel Ọshin

MUHIN.

## A Nfẹ Iwe Irohin Imọlẹ Ni Ilu Ilesha

Olotu/ Jọwọ gba mi laye pẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ rẹ oloyin mọmọ lati kesi awọn alaṣẹ iwe Irohin Imọlẹ ki nwọn jẹki Iwe na deilu wa ni Ilseha.

Iwe na ma nkọ wa ni ọgbọn ati oye pupọ sugbọn ojẹ ohun ti o dun wa pupọ lati ri wipe iwe na ki de lu wa ni Ilesha

Nitorina atẹ awọn alaṣe Iwe Irohin na ki nwọn jẹ ki iwe yi ma de ilu wa lojojumọ.

Mo i fẹ ki ẹniti o ba mọ itan isedalẹ ilu ilesha kọ itan nipa rẹ ranṣẹ si Olotu iwe Irohin Imọlẹ lati fẹ jade fun awọn ọmọ ilu Ilesha.

Inu wa yio dun ti awọn ala-ṣẹ iwe Irohin Imọlẹ ba le jẹki iwe na ma de ilu wa lojojumọ.

Olotu, mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi' ajinde ara yio majẹ o

Emi ni
S.O.Famiyesin

ILESHA.

# Awọn Onişowo Fẹ Pe Ijọba Ibilẹ Abẹokuta Lejọ

ABẸOKUTA:— Laipẹ yi ni awọn onişowo ti nwọn haya awọn ile itaja lọwọ Ijọba ibilẹ ilu Abẹokuta ti gbero lati pe igbimọ Afunşhọ ti Ijọba ibilẹ ilu Abẹokuta l'ẹjọ lori iwe ti awọn igbimọ Afunşhọ na kọ si wọn onişowo mẹtalelogun pe ki nwọn kuro ni awọn isọ ti nwọn haya na ninu oşu yi.

Ninu ọrọ ti Agbẹjọro awọn onişowo na Ọgbẹni Tunde Odubiyi fi ye oniwe irohin wa pe on ti kọ iwe ikilọ kan si awọn igbimọ Afunşhọ ti Ijọba ibilẹ ilu Abẹokuta pe ti nwọn ko ba tete gba iwe ti nwọn fun awọn onişowo mẹtalelogun na pada pe on yio pe wọn l'ẹjọ.

Ọgbẹni Odubiyi tun şe alaye fun oniwe irohin wa pe iwe ti awọn igbimọlẹ afunşhọ ti Ijọba ibi ilu Abẹokuta fun awọn enia on pe ko si ba eto ofin mu rara ati pe awọn enia na ko ti lo asiko tan bi pe awọn onişowo ni kuna lati san owo oşu ti nwọn nsan lori isọ na.

Ọkan ninu awọn onişowo na fi ye onirohin wa pe nitori pe awọn ko şe ẹgbẹ Dẹmọ NNDP lo mu ki Ijọba ibilẹ na ma hu iwa bẹ pẹlu wọn ati pe awọn ti şe tan lati pe awọn igbimọ Afunşh) ti Ijọba ibilẹ na l'ẹjọ bayi.

# Asoju Ọba-Binrin Malawi




Aworan eke yi ni igbati Aşọju Ọbabinrin Gẹẹs Ọmọba Philip nk iwe ti Ọba binrin Gẹẹsi kọ si Ijọba Malawi ati awọn enia ati Orilẹ ede na fun ikini pe mo ba ọ yọ l seko ti Orilẹ ede Malawi gba Ominira.

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Işẹ ti o kọ ti o nşe lọwọ ko ni lọ deede, maşe fi aye sile fun imẹlẹ bẹni ki o maşe şọle Ire agbayaun kan yio yẹ sio lalẹ oni.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Gbogbo işẹ ti oba dawọle loni Ire ni yio jẹ fun iwọ ati ọrẹ rẹ lọkunrin, nitoripe Adanu diẹ ti o ba pa, koni duro mọ ni kekere.

ARIAS (May 21-April 20) Ọrọ ija kan yio şẹlẹ, maşe dasi, bi oba ti jẹ wipe, ko dişẹ tirẹ lọwọ. Bi o ba tete sun lalẹ oni, iwọ yio bọ kuro ninu Ijangba ti o ni lati de si ọ ni alẹ ọjọ oni na

TARUS (April 21-May 20) Irẹpọ iwọ pẹlu ẹnikan yio jẹ ti ọna odi nitori kingbọ king'a ni wọn. Koiti si idide kau fun ọ nikan ibiti o nfẹ lọ.

GEMINI (May 21-June 21) Ko si ọna aşeyọri fun ọ loni, şe sun, ki o si ro arotunro rẹ, ki olo ọgbọn ori rẹ lati mọ eyiti oyẹ ki o pati ninu işẹ rẹ na kio si şe eyiti ojẹ pataki.

CAUCER (June 22-July 23) Oyẹ ki o ronu wo daradara ki o to fi işẹ rẹ silẹ lọ şe om ran bi bẹ kọ işẹ ijọgbọn ni eyiti o fẹ lọ şe

LEO (July 24-Aug 22) Iwọ yio gba awọn alejo enia sinu ofin rẹ loni gba awọn alejo re gbọ ki o si gbekẹ le wọn.

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Ọjọ re ni ọjọ oni jẹ fun ọ ere jijẹ si ibẹ fun ọ Şe adenun patiki pẹlu awọn ti o nba şişẹ Işẹ r yio yọri si rere

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Ajọşepọ iwọ pẹlu ẹnikan ko le juşe loni, maşe ba ẹnikan gbonu tabi Ija ki o ma ba sopa, şọra lọdọ Obinrin ti o nba şe ọrẹ.

SCORPIO (Dec 24 - Nov 22) Aiye ndara fun ọ loni bi o ba le pade ẹnikan ti omura tan lati şe iranlọwọ fun ọ, şugbọn ọgbọn ni ki o lo nipa ọrọ na

SAGITTARIOUS (Nov 23 - Dec 21) Şe ara giri, ki o si tọju işẹ rẹ nitoripe iwọ yio gọọ irohin ti ko dun mọ ọ nnu, maşe foiya, masi şe banujẹ.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Bi ba şe akiyesi pe işe ti o nşe yi, iwọ yio ri owo nibẹ, maşe e nişo, maşe binu, ma si şe ja igbẹhin rẹ yio dun bi oyin.


MAFI OWO RẸ ŞE "OFO" MỌ NIPA RIRA AWỌN KỌBIRỌBI TỌNIKI NITORIPE OWO WỌN RỌJU ARA RẸ LO NSE IYẸN DAJU O BẸRẸ OJỌLO KO H UNHAUN AYONRAN TỌNIKI TI WỌN NPE NI

## "MINOPHOS–TONIKI"




Aworan ẹgbẹ yi fi han ọ gbangba bi ẹda eni ti ri laisi "ẸRAN ARA" atipe ojulowo tọniki to le şe işẹ ribiribi ni ẹjẹ ara, işọri ara ninu egungun gẹgẹbi aworan yi to fi han ọ, MINOPHOS Tọniki a ma ẹjẹ fa titun si ara, papa ti enia ba nru siogurodo tabi fun wahala işẹ şişe aiko nri orun sun daradara to, bẹni o si darajulọ pẹlu bi ara enia ba nbena nigbakugba tabi lehin aisan tabi amodi bi igbona, iba pọnjupọnju tabi a a wiwo enia nigbaku gba,

At fun işọn a lokun ati egungun ara ti o ba dabi ẹnit pe omurọ tab ti ko la gbara to. Şi dan igo kan egbogi tọniki yi wo iwọ yio si ma rohin rẹ fun gbogbo enia pẹlu. Bere ni Şọbu awọn:–

WATERLOO (SH P) MEDICINE STORES
8, PALMCHUCH STREET LAGOS
P, O, BOX 333

# Adeosun Fagbenro Joye Olori Orodan Egungun

EKO:— Irohin ko to afojuba ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni adugbo nomba 54, Evans Street Eko nigbati Ọgbẹni Adeoṣun Fagbenro joye Olori Orodan Egungun ti Eko ati agbegbe rẹ ki ẹyẹ eto ifi ni joye na to bẹrẹ ni awọn Egungun lati Muṣhin, Agarawu, Agbole Oya Okepopo, Agbole Ope ati Agbole Elemele ni ile Egungun kan ti nwọn npe ni Ologbojo ti bẹrẹ si ni jo kakiri adugbo Evans pẹlu awọn ọmọde lẹhin wọn pẹlu ilu oriṣiriṣi.

Nigbati o nto bi deede agogo marun abọ irọlẹ ni awọn Alakoso Egunguu bẹrẹ si ni de si ile Oloye pelu egungun kan ti orukọ rẹ njẹ Agbọmọla ti o wa niiwaju awọn enia na pẹlu Alagba awọn Egungun ọgbẹni Ayinde Giwa.

Gẹgẹbi awọn enia na ti nwọn jẹ Oloye ninu awọn okunrin ati lobinrin si to si lẹhin Egungun Agbọmọla bi awọn Awo Egungun na ti nto lọ lẹsẹsẹ ni nwọn nṣe awọn eto ba ti iṣẹdalẹ ti nwọn fi njẹ oye ninu Egungun bọ pẹlu Alaga awọn Egungun ti Eko atagbegbe rẹ Ọgbẹni Ọmọṣuagọ Falade, lẹhin ti awọn enia nwọnyi de ile Oloye titun na ni awọn enia nwọnyi ninu awọn to jẹ Oloye ninu Egungun lo ṣe eto iṣẹdalẹ ti nwọn fi njẹ oye ninu Egungun fu ọgbẹni Adeosun Fagbenro niuu yara kan ni ilẹ rẹ.

Awọn enia toba ṣe ẹto to iṣẹdalẹ na lọ mi Akindele



Oloye D. Iroko
Olori Ewọn Alegun.

Awo ti o jẹ Ọlọta ninu oye Egungun, Jibirila Falade, Ayinde Adegbula ti ojẹ Atọkun Egungun, Francis Ogun ti ojẹ Omilẹ ninu oye Egungun gbogbo awọn Oloye na lo si ṣẹ etutu fun Oloye titun na.

Ni ọjọ keji ti iṣe ọjọ Iṣẹgun ọjọ kẹsan oṣu yi ni awọn Egungun na tun bẹrẹ si jo pẹlu ilu ti nwọn tun bẹrẹ si ba ero etutu wọn lọ lori ifi ni joye na. Ni ọjọ na ni oloye Iroko ti ojẹ olori awọn Egungun ṣe gudugudu meje si ile Oloye Fagbenro ni ọjọ na. Oloye Fagbenro fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ Oye na l'oru ti o fi jẹ pe awọn enia na ko le kuro nibi eto Oye na laseko ti o yẹ ki nwọn fi ibẹ silẹ.

Ọpọlọpọ awọn Oloye ninu Egungun lọkunrin ati lobinrin lo si wa sibi eto Ifini joye na ninu wọn ni Adukẹ Elemele Iya Ẹgbẹ Segilọla Morgan ti o jẹ Akewe Obinrin, Adunni Awo, Abadatu Alaran, Ajinwun Jeminatu Adegbọla, Adunlọla, Aina, Oke Ọpẹọla Dada Irọko, Ambọja Irọko Ogunbamibi Irọkọ, Sabale Irọkọ awọn eeyi ni Oloye ninu Egungun ti ojẹ obinrin Awọn oloye ọkunrin ninu Egungun to wa sibi ẹyẹ oye na ni ọjọ Awo ti o jẹ Eyishọruo Akindele Awo ti ojẹ Ọlọta Latunji Farẹmi Ayinde Adegbọla ti o tun jẹ Atọkun Salami Olokọ ti o jẹ Aiko ninu oye Egungun Rasaki Elemele ti o jẹ Akẹrẹ Wabi Adeyẹ ti o jẹ Akewe Egangun fun ọkunrin Francis Oun tio jẹ Omilẹ Egunguo S. B. Elebute Akanni Taylor, Alao Tade, Ṣẹkinnni Akanni, Benard Iroko Suie Padoni Tunde Irọkọ Semeon Irọkọ ati Adejumọ Adeyẹmi

Awọn oloye ninu Egungun nwọn yi si ṣe adura fun gẹgẹbi isẹdalẹ eto Egungun oloye titun na,

## Oloye Fashanu Tun J'oye Titun Miran

ABẸOKUTA:— Irohin ko tọ afojuba lẹnulọyi ni ilu Abẹokuta nigbuti Alaga ile iṣẹ itẹwe ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati Alaga ẹgbẹ ọdọ kan ti a npe ni (Zikist Movement) ọkun ninu ẹka ẹgbẹ Alakukọ Oloye Adewale Faṣhanu ni irohin tun fi ye wa pe o tun jẹ oye titun kan gẹgẹbi Ntabo ti Ijeun ni Abẹokuta.

Lẹnulọlọyi na ni oloye Adewale Fashanu di Basala ti ikija ni ilu Abẹokuta Ẹjẹ fi mi joye na ni nwọn ṣe ni ile awọn ogboni ni Ijẹun Abẹokuta eyiti gbogbo adugbo kun fun awọn ọrẹ ati awọn ẹbi oloye titun na ti nwọn wa lati wa ba oloye na se aeyẹ ẹyẹ oye titun na.

Lẹhin ẹyẹ fimi joye na ni ilẹ awọn ogboni ni awọn ẹbi ati alabaṣẹyẹ si to lọ si afin Ọbb ni Ake Abẹokuta nibi ti nwọn ti se awọn eto isẹdalẹ to kan tun oloye na eyiti oloye iva af... Labọde ti o jẹ Musade ti Ake fi ewe akoko oye le oloye titun na lori

Ninu ọrọ rẹ aibi ẹyẹ oye na Ọba Gbadebọ keji Alake ti ilu Abẹokuta se apejuwe oloye Adewale Fashanu gẹgẹ bi ọmọ kan ti o jẹ ọmọ rere ni arin ilu Abẹokuta ati ilu agbegbe ilẹ Ẹgba Ọba Alake tun sọ fun gbogbo awọn nkan risisi awọn ohun to jẹ ilasiwaju ti oloye Fashanu se si ilu Ẹgba

Ọba Gbadebo keji tun sọ siwaju si pe oye ti Oloye Fashanu jẹ yi wa gegẹbi eto ilana ihun rere ti yio ma wọ ilu Ẹgba.

Ọpọlọpọ awọn enia jankanjankan lo wa sibi ẹyẹ oye na ninu wọn ni Ọba awọn Ijọye, ati awọn Alakoso ni awọn ile iṣẹ gbogbo ni jake jade orilẹ ilẹ Naijiria. Awa Oniwe Irohin Imọlẹ na bbadura fuu Oloye titun na pe ori ewe oye a mọri O Amin.

## Ayunọrunbọ Ati Panpalaso

Lati Oju Ewe Keji

Ayunọruubọ ati panpalaso jade tabi koi ti jade, inu mi dun pe awọn onkawe irohin Imọlẹ mo ri ni itan ma, lagbara Oluwa laipẹ yi nigbati mo ba pari itan yi ng'o tẹẹ jade fuu titu ni owo pọọku

Esu gbe ẹtan rẹ de ni ẹkẹta. Nigbati Ayunọrunbọ fa wọn yọt e ninu ọgbun aiṇireri yi ofi ọ a ọrun han wọn wọn sin mi

diẹ fun gbogbo wahala ti oju wọn tiri bi wọn siti nlọ ga ga ga ni wọn ba ọkunrin arẹwa gbọgẹdọ kan pa de ope wọn, sugbọn wọn ko da lohun otun pe wọn lẹẹkeji wọn ko tun dalohun bakanna nigbati ose

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 770. FRIDAY, AUGUST 14 1964 (2D)

## Awọn Ełẹwọn Mẹfa Sa Kuro L'ọgba Ewọn.

IKOYI:- Ni ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ ketala oṣu yi ni irohin de ọwọ wa lati ọ ọ Alakoso ọgba ẹwọn ti Ikoyi l'Eko pe awọn Ẹlẹwọn mẹfa kan sa kuro lọgba ẹwọn ati pe awọn olusọ awọn ẹlẹwọn to wa lọgba Ẹwọn na ko si mọ akoko ti awọn Ẹlẹwọn mẹfa na ri aye jade tabi ibi ti awọn Ẹlẹwọn na gba jade ko si ye awọn Olusọ ọgba ẹwọn na ni akoko ti nwọn jade kuro ninu ọgba Ẹwọn na.

Irohin na tun fi ye wa pe Alakoso ọgba Ẹwọn ni ikoyi si ti pa l'aṣẹ fun awọn olusọ ọgba Ẹwọn na ki nwọn bẹrẹ lati ma wa gbogbo adugbo boya nwọn le ri ninu awọn Ẹlẹwọn na bayi

Nigbati oniwe irohin wa lọ si ọgba Ẹwọn na lati lọ ṣe wadi gẹg bi awọn Ẹlẹwọn na ṣe gba jade lati ọwọ Alakoso eto ọgba Ẹwọn to wa ni Ikoyi, ọkan ninu awọn aṣoju awọn Ẹlẹwọn na fi ye oniwe irohin wa pe ko le ri Alakoṣo ọgba Ẹwọn bayi. Sugbọn olusọ awọn Ẹlẹwọn na fi ye oniwe irohin wa pe awọn ti nṣe eto ọna gẹgebi nwọn yio ṣe le ri awọn Ẹlẹwọn na. Oniwe irohin wa fi ye wa e wọn ko ṣọ orukọ awọ nẸlẹwọn na fun on-

**Aminu Kano Sọ Pe:**

# Ẹgbẹ N.P.C. Ti Fun Akintọla Ni Owo Lati Gbogun Ti Enia Iwọ Orun

KANO:- Olori ẹgbẹ NEPU (Nigeria Element Progressive Union) ati Alaga ẹgbe kan ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ti a npe ni (Northern Progressive Front) N. P. F. Alhaji Aminu Kano sọ ninu ọrọ re ni Kano pe ẹgbẹ Olomi NPC ti fun Alakoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, ati Olori ẹgbẹ Dẹmọ NNDP Oloye S L. Akintọla ni owo to to bi (£1, 500, 000) lati fi gbogun ti awọn enia ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Alhaji Aminu Kano ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ nsọrọ ni Kano pe ninu owo ti awọn ẹgbẹ Olomi NPC fun oloye S L Akintọla jẹ ninu owo ori ti awọn enia ipinlẹ Ariwa ko jọ fun eto lati le jẹ ilọsiwaju wa fun ilu na.



Oloye S. L. Akintọla

Alhaji Aminu Kanu sọ pe eleyi jẹ ohun to ya on l'ẹnu lati ri pe iru owo to pọ jaburata bayi ni nwọn yio fun ẹgbẹ oṣelu kan ti awọn enia ko ma rara gẹgebi ẹgbẹ eyiti Oloye Akintọla nṣe olori rẹ ẹgbẹ Dẹmọ (N. N. D P.) Alhaji Aminu Kanu sọ pe nigbati ko i ile ẹkọ fun awọn ọmọ lati lọ kọ ẹkọ ati pe ọpọlọpọ awọn enia ni ko ri iṣẹ ṣe ni Ipinlẹ Ariwa bayi.

Siwaju sii Alhaji Aminu Kano sọ pe ẹgbẹ on Northern Progessive Front NPF nikan lo le mu eto alafia ilọsiwaju ati ijọba rere wa fun awọn enia ipinlẹ Ariwa Naijiria.



Alhaji Aminu Kano

Alhaji Aminu kano sọ pe on gba awọn enia ipinlẹ na ni iyanju lati le ri wọn pe nwọn fi tọkantọkan dibo fun ẹgbẹ (N P F) lasiko idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria eyiti idibo rẹ yio waiye larin ọdun yi lati le jẹ ki eto alafia ati Ijọba rere wa ni ipinlẹ na.

Siwaju si Alhaji Aminu Kano ro gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ ẹ ti yio gbe apoti ibo silẹ laseko idibo si ile igbimọ asofin ti apapo Ijọba ilẹ Naijiria lati sọra gidigi li lọ wọ awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi N. P. F. to ba di aseko ibo ati ti nwọn ba le bori ibo na ki nwọn ma ṣe iye meji lati tun sọ pe nwọn tun lọ ba ẹgbẹ Olomi lori ohun kohun ti nwọn ba le fun wọn.

Ninu ọrọ ti Alhaji Aminu Kano sọ pe ẹgbẹ Olomi sọ pe on fẹ ta Ipinlẹ Ariwa fun awọn enia Ipinlẹ Gusu ilẹ Naijiria, Alhaji Aminu Kano sọ pe ẹni to ba ni ohun to le ta lọwọ ni yio sọ pe on fẹ ta nkan ati pe irọ patapata ni ọrọ ti awọn ẹgbẹ Olomi sọ.

Alhaji Aminu Kano fi ye awọn enia rẹ pe ẹgbẹ Olomi N, P. C. to si nṣe akoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ati pe awọn lo mọ nkan ti nwọn le fi awọn ipinlẹ na ṣe Alhaji Aminu Kano sọ pe awọn ẹgbe no ko ni ero lasi ta ipinlẹ Ariwa rara ati pe gbogbo awọn ti Ọmọ ẹgbẹ ti nṣe akoso ipinlẹ na.

Lati Oju Ewe Kini

na ni ile igbimọ asofin ti ipinlẹ Ila Orun eyiti o dibo wọle igbimọ na to duro degegbe fun rarẹ eyiti ẹgbẹ na si yọ kuro l'ẹgbẹ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na si fẹ gba pada sinu ẹgbẹ na ọgbẹni Samuel Mgbada ti o wọle ni agbegbe Izza ni ila Ila Orun ti ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo ẹgbẹ o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiyẹ ni ọjọ kọkandelogun oṣu (16/8/64) ni deede agogo meji ọsan ni Iọmba 16, Bamgbose Street Lagos.

Ao tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ ki ẹsi tete de

LATEEF BABALOLA
Akọwe Agba

## Awọn Ehanna Ẹgbẹ Oselu gbogun Ti Awọn Ọlọpa

Lati Oju Ewe Kini

do awọn ọlọpa na oniwe irohin wa tun fi ye wa pe oga awọn ọlọpa ti Ijọba ibilẹ on wa ti ibudo awọn Ọlọpa nigbana Ọgbẹni Ezekiel Taiwo si fi ara gbọgbẹ nigbati awọn Ẹhanna na si bẹrẹsi ba a ja eyiti nwọn fi gbe e lọ si ile iwo san ti Adeọyọ ni Ibadan.

Irohin tun fi ye wa pe okunrin kan ti ile rẹ wa ni tosi ibubo awọn Ọlọpa to si lo ẹrọ ifi iranṣe ranṣẹ si ọgba awọn Ọlọpa ti ilẹ Naijiria ni ibudo wọn ṣugbọn ki awọn Ọlọpa yi to de ibudo awọn Ọlọpa na ti awọn Ẹhanna na ti salọ Irohin fi ye wa pe awọn Ọlọpa si mu ọkan ninu awọn enia na ti nwọn si ti mọle ni ibudu awọn Ọlọpa ti rogbo 'iyan ti ṣẹlẹ.

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 14/8/64.